# ÀLÌKÁMÀ ATI ÈPÒ
## Matteu 13:24-30, 36-43
### ẸKỌ 76 FUN AGBA

**AKỌSORI: "Kó awọn enia mimọ́ mi jọ pọ̀ si ọdọ mi: awọn ti o fi ẹbọ ba mi da majẹmu"(Orin Dafidi 50:5).**

**I Irugbin Rere ti a Gbin Sinu Oko**

1. A fi Ijọba Ọrun wé owe ti èpò, Matteu 13:24, 25
2. "Ọkunrin" naa ti o gbin irugbin rere ni Ọmọ-eniyan, Matteu 13:24, 37; 18:11
3. "Oko" naa ninu eyi ti a gbin irugbin si ni aye, Matteu 13:24, 38; Orin Dafidi 2:8
4. "Irugbin rere" naa ni awọn ọmọ Ijọba, Matteu 13:24, 38; Romu 8:16

**II Èpò ti a Gbin saarin Alikama**

1. A gbin awọn epo naa nigba ti eniyan sun (oorun ti ẹmi), Matteu 13:25; Isaiah 60:2; 1 Tẹssalonika 5:6
2. "Èpo" naa ni awọn ọmọ ẹni-buburu nì, Matteu 13:25, 38; Johannu 8:44
3. "Ọta" naa ti o gbin èpò buburu naa ni èṣu, Matteu 13:25, 39; Efesu 6:11

**III Ipinya nigba Ikore**

4. Igbẹyin aye ni "Ikorè", awọn angẹli si ni awọn "olukore", Matteu 13:30, 39; Marku 13:27
5. A ko le tu èpo kuro ki a ma ba tu alikama pẹlu, Matteu 13:28, 29; Iṣe Awọn Apọsteli 15:14-17
6. Ipinya ikẹyin yoo de nigba ikore, Matteu 13:30; 25:31, 32; Daniẹli 12:2
7. A kó awọn "èpo" jọ a si fi iná (ina ainipẹkun) sun wọ́n, Matteu 13:30, 40-42; 25:41
8. A ko "alikama" jọ sinu "abà" Rẹ̀ (eyi ti i ṣe Ijọba Baba wọn), Matteu 13:43; Daniẹli 12:3

## ALAYE

Gẹgẹ bi owe Afunrugbin, Oluwa tumọ owe Alikama ati Epo. Nitori naa ko yẹ ki a ṣiyemeji itumọ wọn. A ri i pe ekinni n sọ nipa iru ọkàn ti awọn eniyan fi n gba Ọrọ Rẹ̀ -- o si jẹ́ ohun danindanin, nitori nipa gbigba a ni a fi le wọ Ijọba Ọrun. Owe keji yii si tẹle e bi o ti yẹ nitori o n sọ nipa igbesẹ siwaju si i nipa Ijọba naa, o n fi igbẹyin awọn ti o jẹ́ "ilẹ rere" hàn, ninu ọkàn awọn ti a gbin Ọrọ Rẹ̀ si.

### Irugbin Rere

Gẹgẹ bi ti owe akọkọ, "Afunrugbin" nihin ni Ọmọ-eniyan (Matteu 13:37), "oko" ti a gbin irugbin rere naa si ni ayé (Matteu 13:38), "irugbin rere" si ni awọn ọmọ Ijọba naa gẹgẹ bi Oluwa ti ṣe alaye.

Nipa bayii, owe yii fi idi pataki ti Jesu fi wá sinu ayé hàn gẹgẹ bi Simoni Peteru ti royin laaarin igbimọ ni Jerusalẹmu nigba ti o n jẹri nipa ibẹwo rẹ̀ si ile Kọrneliu, gẹgẹ bi ọrọ ti Jakọbu tun sọ pe: "Simeoni ti rohin bi Ọlọrun li akọṣe ti bojuwò awọn Keferi, lati yàn enia ninu wọn fun orukọ rẹ̀" (Iṣe Awọn Apọsteli 15:14). Nigba ti Jesu Kristi Oluwa de, oore-ọfẹ igbala de ọdọ awọn Keferi. Lati bi ẹgbaa ọdun sẹyin ni Ọmọ eniyan ti n wá "awọn enia kan fun orukọ rẹ̀." Awọn wọnyii ni "awọn ọmọ Ijọba naa" ti a yàn lati aarin ẹ̀yà ati orilẹ-ede gbogbo wá. "Oluwa na si wi fun ọmọ-ọdọ na pe, Jade lọ si opópo, ati si ọ̀na ọgbà, ki o si rọ̀ wọn lati wọle wá, ki ile mi le kún" (Luku 14:23). Iṣẹ yii yoo maa lọ bẹẹ titi ẹni ti o joko lori aga ti o kẹyin nibi "Ase-alẹ igbeyawo Ọdọ-agutan" yoo fi dé.

### Epo laaarin Alikama

Ṣugbọn bi a ti n ba iṣẹ fifún "irugbin rere" yii lọ bẹẹ ni iṣẹ miiran tun n lọ ni ikọkọ "nigbati enia sùn." Gẹgẹ bi a ti sọ fun wa, "èpo" ninu owe yii ni awọn ọmọ ẹni buburu nì (Matteu 13:38), "ọta" ti o si gbin wọn ni eṣu (Matteu 13:39). Lati igba Adamu wa ni eṣu naa ti n wá awọn "ọmọ" fun ijọba ti rẹ̀. Ni Igba aye Oore-ọfẹ yii eṣu n fi itara ṣiṣẹ ju ti atẹyinwa lọ nitori o mọ pe akoko oun kuru. O si ti ni ọpọlọpọ ọmọ-ẹyin "nigbati enia sùn," nitori ọpọlọpọ ni itura ti mu ki o sun oorun ti ẹmi, wọn si wà ni "ọna gbigboro ti o lọ sibi iparun" nisisiyii. Lai pẹ, Satani yoo gbé ijọba rẹ̀ kalẹ fun igba diẹ (Ifihan 13:1-18) lakoko igba ti a o fi "ipọnju nla" bẹ ayé wò. O wà lọwọ awọn eniyan lati pinnu nisisiyii inu ijọba wo ni a o bá wọn ni ọjọ naa.

### Igba Aye Oore-Ọfẹ

Nisisiyii fifún "irugbin rere" ati fifún "èpo buburu" n lọ papọ̀ lọwọ kan naa bi a ti n waasu "Ihinrere Ijọba yi" ká gbogbo ayé (Matteu 24:14). Nigba ti awọn ọmọ-ọdọ baale ile naa ri èpo buburu ninu oko, wọn wi pe "Oluwa, irugbin rere ki iwọ fún sinu oko rẹ? nibo li o ha ti li epo buburu?" O dahun pe, "Ọtá li o ṣe eyi." Awọn iranṣẹ naa wi fun un pe, "Iwọ ha fẹ́ ki a lọ fà wọn tu kuro?" Ṣugbọn oun dahun pe "Bẹ̃kọ, nigbati ẹnyin ba ntu epo kuro, ki ẹnyin ki o má bà tu alikama pẹlu wọn."

Awọn akẹkọọ Bibeli kan ti wọn ti rin irin ajo lọ si Ilẹ Mimọ gbagbọ pe “èpo” ti a darukọ yii jẹ ohun ọgbin oloró kan ti o fẹrẹ má yatọ si alikama nigba ti awọn mejeeji kò ba i ti i so eso, ṣugbọn ti a le tete mọ̀ yatọ nigba ti wọn ba so eso. Nigba pupọ ni a maa n ri i pe èpo yii tànká aarin alikama, a si lọ́ mọ ọn to bẹẹ ti a kò fi le fà a tu lai pa alikama lara, nitori bẹẹ ni o ṣe tọ́ lati duro de igba ikore. Nitori naa Ọlọrun ni O gba “alikama” ati “èpo” ni àyè lati maa dagba pọ laaarin ọpọ oore-ọfẹ igbala Rẹ̀; nitori eyi ni igba fifún irugbin, nigba ti O n pese awọn eniyan kan silẹ fun Ijọba Ọrun naa, ani ninu ayidayida ayé buburu yii. O le ṣe alairọrun lati mọ awọn ọmọ Ijọba Ọrun yatọ si awọn ọmọ ayé nisisiyii bi a o ti mọ wọn yatọ nikẹyin; sibẹ o ṣe e ṣe lati gbe igbesi ayé Onigbagbọ ninu ayika ayé buburu ti a n gbe. “Nitori ore-ọfẹ Ọlọrun ti nmu igbala fun gbogbo enia wá ti farahan, O nkọ́ wa pe, ki a sẹ́ aiwa-bi-Ọlọrun ati ifẹkufẹ aiye, ki a si mã wà li airekọja, li ododo, ati ni iwa-bi-Ọlọrun ni aiye isisiyi” (Titu 2:11, 12). Ọlọrun ti pè wá lati maa ba A rin nisalẹ nihin gẹgẹ bi Enoku igba nì, ki a fa ọkàn wa kuro ninu ayé, ara ati eṣu. Ipe naa n lọ sibẹ kaakiri gbogbo ayé. “Ẹnikẹni ti o ba fẹ” le jẹ ipe naa ki o si di ọmọ Ijọba naa.

**Igba Ikore**

Ṣugbọn ni ọjọ kan “akokò fifunrugbin” yoo dopin, “alikama” yoo dagba a o si kó wọn sinu “abà” Rẹ̀. Baale ile naa sọ fun awọn iranṣẹ rẹ̀ nipa ti alikama ati epo naa pe, “Ẹ jẹ ki awọn mejeji ki o dàgba pọ̀ titi di igba ikorè; li akokò ikorè emi o si wi fun awọn olukore pe, Ẹ tètekọ kó èpo jọ, ki ẹ di wọn ni ití lati fi iná sun wọn; ṣugbọn ẹ kó alikama sinu abà mi.” Oluwa ṣe alaye pe “ikorè” ni igbẹyin ayé; awọn angẹli si ni “olukore”; “abà” ti a kó “alikama” sinu rẹ̀ ni Ijọba Ọrun ti awọn ọmọ Ijọba ti n duro dè, ti wọn si n wọna fún. A o rán idajọ sori awọn ọmọ ẹni buburu nì, ṣugbọn yoo jẹ ọjọ ayọ̀ ati inu didun fun awọn ẹni irapada Oluwa. Nitori ọjọ naa ni Oluwa yoo pada wá sinu ayé lẹẹkan si i, ki i ṣe gẹgẹ bi Ọkunrin ara Nasarẹti onirẹlẹ ṣugbọn gẹgẹ bi Onidajọ gbogbo ayé.

Gbogbo orilẹ-ede ni a o kó jọ siwaju Rẹ̀; yoo si yà wọn sọtọ gẹgẹ bi oluṣọ-agutan ti i ya agutan rẹ kuro lara ewurẹ, awọn agutan ni apa ọtun Rẹ̀ ati awọn ewurẹ ni apa osi. “Nigbana li Ọba yio wi fun awọn ti o wà li ọwọ́ ọtun rẹ pe, Ẹ wá, ẹnyin alabukun-fun Baba mi, ẹ jogún ijọba, ti a ti pèse silẹ fun nyin lati ọjọ ìwa” (Matteu 25:34). “Nigbana ni yio si wi fun awọn ti ọwọ́ òsi pe, Ẹ lọ kuro lọdọ mi, ẹnyin ẹni egun, sinu iná ainipẹkun, ti a ti pèse silẹ fun Eṣu ati fun awọn angẹli rẹ” (Matteu 25:41).

Ọjọ naa i ba jẹ yara de kankan ti a o ri I lojukoju! “A kò si ti ifihàn bi awa ó ti ri: awa mọ pe, nigbati a bá fihan, a ó dabi rẹ̀; nitori awa o ri i ani bi on ti ri” (1 Johannu 3:2). Ni ọjọ naa ni a o mọ “èpo” yatọ si “alikama.”

**“N ko tọrọ adun ayé**

**Bẹẹ ni n ko wá okiki**

**N oo fara da iya fun ọ**

**Ki n sa le maa ba ọ rin.”**

## AWỌN IBEERE

1. Ta ni “afunrugbin” ninu owe yii?
2. Ki ni “èpo,” “alikama” ati “oko” duro fún?
3. Ni akoko igba wo ni ohun ti a kọ silẹ wọnyii ṣẹlẹ?
4. Ki ni ṣe ti a kò le fa èpo tu nigba ti a ri i pe o n dagba pọ̀ pẹlu alikama?
5. Ki ni ṣe ti Ọlọrun fi àye silẹ fun ibi lati maa gbilẹ ninu ayé gẹgẹ bi a ti kọ ọ silẹ ninu Oniwasu 8:11? Apẹẹrẹ ki ni “abà” jẹ?
6. Akoko igba wo ni “ikorè” duro fun ninu owe yii?
7. Ki ni a ṣe si èpo ati alikama nigba ikorè? Ki ni itumọ ohun ti a ṣe si wọn?
8. Sọ ẹsẹ Iwe Mimọ́ kan lati fi idahun rẹ̀ si ibeere oke yii mulẹ.
9. Ki ni ẹlẹṣẹ le ṣe ki o le pada kuro lọdọ ẹni buburu nì wá sinu Ijọba Kristi?
10. Iru igbesi aye wo ni oun yoo maa gbe ki o to lè jogun Ijọba naa nigba ikore?